# Àrokò Gẹ́gẹ́ bí Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Láàárín Àwọn Babaláwo

Olúwaṣakin A. Kẹ́hìndé
Department of Linguistics and African Languages
University of Ìbàdàn, Nigeria.
kennyoluwasakin@gmail.com

## Àsamọ̀

Àrokò jẹ́ ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ nípa ṣíṣàmúlò àmì tàbí èdè awo. Ìran Yorùbá ò fẹ́ràn láti máa fi gbogbo ẹnu sọ̀rọ̀, nítorí náà wọ́n nífẹ̀ẹ́ sí lílo èdè ìjìnlẹ̀ tàbí ohun tí ó ní ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ nínú àṣà wọn fún ìbánisọ̀rọ̀. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ onímọ̀ tí ṣiṣẹ́ lórí pàtàkì àrokò láàárín àwọn Yorùbá àmọ́ ọ̀wọ́já wọn ò tí dé ibi àrokò láàárín àwọn babaláwo. Pépà yìí ṣe àgbéyẹ̀wò àrokò gẹ́gẹ́ bíi ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ láàárín àwọn babaláwo láwùjọ Yorùbá. Tíọ́rì ìmọ̀ ìlò-àmi ni a gùnlé láti fi sọ ìtumọ̀ àwọn ohun èlò ìbánisọ̀rọ̀ láàárín àwọn bábaláwo. Àwọn détà tí a lò ni a gbà lọ́dọ̀ àwọn àṣàyàn babaláwo, èyí tí a sì ṣàtúpalẹ̀ wọn pẹ̀lú tíọ́rì àmúlò. Iṣẹ́ ìwádìí yìí sàlàyé díẹ̀ lára àwọn ohun ìpàrokò, yálà èyí tí o jẹ́ gbólóhùn tàbí èyí tí o jẹ́ ohun èlò àrídìmú tí àwọn babaláwo ń lò fún ìbánisọ̀rọ̀ awo láàárín ara wọn pẹ̀lú ọ̀nà tí wọn ń gbà lò wọ́n. Pépà yìí tan ìmọ́lẹ̀ sí orísìírísìí ohun èlò ìpàrokò àti ọ̀nà tí àwọn babaláwo ń gbà ṣàmúlò wọn fún ìbánisọ̀rọ̀ láàárín ara wọn. Àpilẹ̀kọ yìí fi hàn kedere pé ṣíṣe àmúlò àrokò láwùjọ le ṣe ìrànlọ́wọ́ láti jẹ́ kí á ní àsírí àwọn ohun tí a kò fẹ́ jẹ́ kó hànde. Ó tún jẹ́ kí a mọ̀ pé, kò sí ẹgbẹ́ tàbí àwùjọ kan lábẹ́ àkóso bó ti wù kó rí tí kò ní ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ alárokò láàárín ara wọn.

## Ìfáàrà

Orísìírísìí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ni ó wà ni ilẹ̀ Yorùbá, bí a se ní ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tààrà tí kò rújú, tí ó sì yé tawo-tọ̀gbẹ̀rì, bẹ́ẹ̀ ni ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ alárokò náà wà. Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ alárokò jẹ̀ ọ̀kan lára àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ ohun àsírí. Ipa tí kò lẹ́gbẹ́ ni àrokò ń kó láàárín ẹ̀yà Yorùbá. Ìran Yorùbá kò fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ alárokò torì náà, wọ́n rí i gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí kò se é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn láwùjọ wọn. Ohun gbogbo, yálà èyí tí a le fi ojú rí tàbí ọ̀rọ̀ tí a sọ jáde lẹ́nu ní ó ní ìtumọ̀ ní àwùjọ Yorùbá. Ìran Yorùbá a máa ṣamúlò àrokò

nígbàkúùgbà tí wọ́n bá fẹ́ ẹ́ sọ̀rọ̀ àsírí. Fún àpẹẹrẹ, nígbà tí wọn bá rán ọmọ nísẹ́ tí wọn ko sì fẹ́ jẹ́ kí ọmọ náà mọ̀ nípa ohun tí wọ́n rán an, wọn yóò pa iṣẹ́ náà lárokò fún ẹni tí wọ́n fi rán, ó le jẹ́ ọ̀rọ̀ ẹnu, tàbí ohun àrídìmú kan tí kò ní ìtumọ̀ sí ẹni tí a fi rán, ṣugbọ́n yóò ní ìtumọ̀ kúkún sí ẹni tí a fi rànṣẹ́ sí.

Onírúurú iṣẹ́ ni àwọn onímọ̀ bíi Abimbola (1975), Ògúndèjì (1988), Alamu (2010), Adésànyà (2014), Àkàngbé (2014) ti ṣe lórí àrokò, ṣùgbọ́n kò sí èyí tí ó sọ̀rọ̀ rẹpẹtẹ ní abala ìlò àrokò gẹ̀gẹ̀ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ láàárín àwọn babaláwo ní àwùjọ Yorùbá. Babaláwo jẹ́ ìránṣẹ́ ìṣẹ̀dálẹ̀ tí a yàn láti dúró gẹ́gẹ́ bíi alárinnà láàárín Ifá àti ẹ̀dá ènìyàn. Wọ́n máa ń bẹ̀bẹ̀ fún ìgbáyé-gbádun ẹ̀dá ènìyàn, onírúurú ìpèdè alárokò ni ó ṣodo sí ẹnu àwọn babaláwo, wọn sì máa ń ṣàmúlò rẹ̀ nígbàkúùgbà láàárín ara wọn. Bì àwọn babaláwo ṣe ń ṣàmúlò àrokò fún ìtàkùrọ̀sọ, bẹ́ẹ̀ ni àwọn olórìṣà yòókù bíi Oníṣàngó, Olórìsà ńlá, Ọlọ́ya, Elégún, Ọlọ́ṣun àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ kò gbẹ́yìn nínú ṣíṣamúlò àrokò gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀. Fún ìdí èyí, ìwádìí yìí ṣàgbéyẹ̀wò àrokò, pàtàkì rẹ̀, àti ìlò rẹ̀ láàárín àwọn babaláwo ní àwùjọ Yorùbá. A óò sì ṣàlàyé àwọn ohun èlò tí àwọn babaláwo ń lò fún ìpàrokò lọ́kan-ò-jọ̀kan nípa lílo tíọ́rì ìmọ̀ ìlo-àmì.

## Tíọ́rì Ìmọ̀ Ìlo-àmì

Eco (1976:7) pè tíọ́rì yìí ní “science of sign” “ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa àmì”. Ọ̀kan lára tíọ́rì tí ó ń se àmúlò àmì fún ìbánisọ̀rọ̀, tí àwọn ènìyàn ń lò láti ní òye, èrò, àti ìmọ̀ ni tíọ́ri ìmọ̀ ìlò-àmì jẹ́. Onìrúurú ẹka-ìmọ̀ ńlańla bíi lítíréṣọ̀, ẹ̀kọ́ nípa àwùjọ, àṣà àti ìdàgbàsókè (Anthropology), ẹ̀kọ́ nípa àwujọ (Sociology), àti àwọn ẹka ìbánisọ̀rọ̀ lónírúurú ni wọ́n ti ṣàmúlò tíọ́rì yìí. Tíọ́ri ìmọ̀ ìlò-àmì máa ń se ìwòye àṣà àti àwọn ọgbọ́n tí ó farasin sínú èdè, iṣẹ́-ọnà àti àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ mìírán. Eco (1976:7) wí pé, “semiotics is a discipline for studying everything which can be used in order to lie”. Ní èyí tí ó túmọ̀ sí pé, “Tíọ́ri ìmọ̀ ìlò-àmì ni ẹka tíọ́rì tí a ti ń kọ́ nípa ohun gbogbo tí a le lò láti parọ́”. Ògúndèjì (1988:8) sàlàyẹ́ bí a ṣe ṣètò “sẹmíọ́lọ́jì” and “sẹmiotiiki” (semiology” and “semiotics) ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Ó wí pé “Onímọ̀ nípa ẹ̀dá èdè tí orúkọ rè ń jẹ́ Ferdinand de Saussure pè é ní “semiotiiki” nígbà tí Onímọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò kan láti ìlú Amẹrikà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́, Charles Sanders Pierce, pè é ní sẹmíọ́lọ́jì”. Ògúndèjì (1988) fi yéwa pé, àwọn ọ̀rọ̀ méjééjì “sẹmíọ́lọ́ji àti “semiotiiki” ni a ń lò láti rọ́pò ara wọn. Orísìírísìí onímọ̀ bíi Bakony (1974), Eco (1976), Ògúndèjì (1988), Manetti (1997), Baltzer (2001), Cobley (2001), Marcel (2004), Ricardo àti Joao (2007), Shaleph (2008), Elliot (2010), Fákẹyẹ (2013) àti Akàngbé (2014) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni wọ́n ti ṣe àmúlò tíọ́ri ìlò-àmì. Ó jẹ́ ohun tí ó gbajú-gbajà ní àwùjọ ọ̀làjú tí ó sì ń fún ènìyàn ní ìmọ̀ bí ó ti yẹ, ó wúlò ní ibi gbogbo tí ẹ̀dá ènìyàn wà bíi, gbọ̀ngàn ìwòran , gbọ̀ngàn eré, ilé ijó, àwòrán ilé yíyà, síṣehun lọ́sọ̀ọ́, òṣèlú, etò ìléra, ìtàn àti ẹ̀sìn. A máa ń lò ó gẹ́gẹ́ bí ohun èlò láti rọ́pò nǹkan

kan tàbí fún ìtumọ̀ ohun kan. Fún ìdí èyí, a le è lo àwọn ohun kékéèké bíi ọ̀rọ̀, àwọ̀, ìró ohùn àti àwọn ohun èlò mìíràn fún àrokò pípa.

Ó ṣe pàtàkì láti sọ ọ́ di mímọ̀ fún wa pé tíọ́ri ìmọ̀ ìlò-àmì pín sí ẹ̀ka mẹ́ta; àmì ìbáṣepọ̀ a-ṣedúró-fún, àmì ìbáṣepọ̀ atọ́ka ìṣẹ̀lẹ̀, àti àmì ìbáṣepọ̀ apàrokò. Ìṣẹ́ wádìí yìí yóò gùnlé ẹ̀ka kẹta tí i se àmì ìbásepọ̀ apàrokò. Nígbà tí Ògúndèjì (1988) ń sàlàyé àrokò gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀, kò ṣàìmẹ́nu ba ìtọ́kasí gẹ́gẹ́ bí ẹ̀wọ̀n tó so àrokò àti ìtumọ̀ rẹ̀ pọ̀. Àmì le má jẹ́ ohun àrídìmú kan pàto, ó le jẹ́ èrò, ìṣe tàbí ọgbọ́n, níwọ̀n ìgbà tí ó bá ti jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà lááárín àwùjọ, ó ti di àrokò fún irúfẹ́ àwùjọ bẹ́ẹ̀.

## Àrokò/Ìtọ́ka àlárokò

Ògúndèjì (1988:48) ṣàmúlò ọ̀rọ̀ Sófolú (1983) àti Ọ̀pádọ̀tun (1986) tí ó wí pé, àrokò is a "Yorùbá indigenous semiotic system where objects are used as a signifiers of certain "messages" transmitted between an addresser and adressee". Èyí ni pé, "àrokò jẹ́ ọ̀nà abínibí Yorùbá fún ìmọ̀ ìlò- àmì, nígbà tí à bá lo ohun kan gẹ́gẹ́ bí àmí láti tọ́ka sí nǹkan "ọ̀rọ̀" láti ọ̀dọ̀ ẹni tí ó fi ránṣẹ́ lọ sí ọ̀dọ̀ ẹni tí a ránṣẹ́ sí". Nígbà tí a bá ń sọ nípa àrokò, àmì tí à ń lò láti pàrokò le má fi ọ̀nà kankan jọ ohun tí à ń wí, ṣùgbọ́n wọ́n jẹ́ ohun tí àwùjọ tẹ́wọ́ gbà láti lò gẹ́gẹ́ bíi àmì. A ṣẹ̀dà àrokò láti inú àwọn àmì mìíràn pàápàá jùlọ láti inú èyí tí a pè ní àmì ìbáṣepọ̀ a-ṣedúró-fún (icon mode). Chandler sọ nínú Peirce (1931:202) wí pé, "the historical evidence does indicate a tendency of liguistics signs to evolve from indexical and iconic forms towards symbolic forms". Èyí ni pé, "àrídájú ìtàn tọ́ka sí pé ó ṣe é se kí àrokò inú ìmọ̀ èdè jáde wá láti inú àmì ìbásepọ̀ a-ṣedúró-fún (icon mode), àti àmì ìbáṣepọ̀ atọ́ka ìṣẹ̀lẹ̀ (index mode) lọ sí àmì ìbáṣepọ̀ apàrokò (symbol mode). Àmì àwùjọ máa ń ṣàfihàn irúfẹ́ àwùjọ tí ó jẹ́. Àjàyí (2003: 46) sọ pè,

> The self-illumination of society through symbols is an integral part of social reality, and one even may say it's essential part, for through such symbolisation the members of a society experience it more than as an accident or convenience; they experience it as of their human essence…As a consequence; every human society has an understanding of itself through a variety of symbols…
>
> (Ṣísàfihàn àwùjọ fúnra rẹ̀ nípaṣẹ̀ àrokò jẹ́ ara ohun pàtàkì fún àrídájú bí àwùjọ ṣe rí gan-an, kódà a le pè é ní ẹ̀ka pàtàkì jùlọ, torí pé nípaṣẹ̀ irúfẹ́ ìpàrokò yìí ni àwọn ènìyàn àwùjọ ti ní ìrírí ju ṣíṣe àrìnnàkò lọ; wọ́n ní ìrìrì rẹ̀ gẹ̀gẹ̀ bíi ẹ̀dá pàtàkì tí wọ́n jẹ́...Gbogbo àwùjọ ẹ̀dá ní ó sì ní òye ara rẹ̀ nípaṣẹ̀ onírúurú àwọn àrokò.)

Whitehead (1928), gẹ́gẹ́ bí Myers (1952) ti sàlàyé, wí pé:

> The art of free society consists first in the maintaining of the symbolic code and secondly in fearlessness of revision, to secure that the code serves those purposes which safety and enlightened reason. Those society which cannot combine reference to their symbols with freedom of revision, must ultimately decay either from anarchy.
> (Ní àkọ́kọ́, ìrísí àwùjọ wà nínú ṣíṣe ítọ́jú àrokò rẹ̀, ìkejì, nínú èrò láti ṣe àtúnṣe, kí á rí i pé àmì náà ṣiṣẹ́ ààbò àti ìkọ́ni. Àwọn àwùjọ tí kò le tọ́ka sí àwọn àrokò wọn, tí wọn kò sì ní àǹfààní láti ṣe àtúnṣe, ó di dandan kí àwùjọ náà dàrú nípasẹ̀ àìlófin).

Àyọlò òkè yìí ṣàlàyé pàtàkì mímú àrokò àwùjọ lọ́-kùn-kún-dùn gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti gbé àwùjọ ró, nígbà ti kíkọ etí ikún sí i yóò mú ìbàjẹ́ àti ìparun bá irúfẹ́ àwùjọ bẹ́ẹ̀. Gbogbo orílẹ̀-èdè ni ó ní àrokò wọn. Àrokò ni àsìá àti orin Orílẹ̀-ede, wọ́n sì ní ohun tí ó ń tọ́ka sí.

Àrokò dúró fún ohun kan pàtó, ní ọ̀nà tí ó se ìtẹ́wọ́gbà ní àwùjọ tí a ti lò ó. Èyí ló jẹ́ kí Ricardo àti Joao (2007:27) sọ nínú ìfọ̀rọ̀wérọ̀ wọn pé “a symbol refers to an artificial or conventional (by virtue of a law) interpretation of a sign”, “Àrokò ń tọ́ka sí ohun kan tí a ṣẹ̀dá tàbí àmì tí a túmọ̀ (nípasẹ̀ òfin) nípasẹ̀ ìgbàgbọ́ àwùjọ”. Ní àfikún, Ògúndèjì (1997:151) wí pé, “the symbolic-object or its content may however vary from one geographical context to another” Ohun tí a ń lò fún àrokò le yàtọ̀ láti agbègbè kan sí òmìràn”. Cassirer (1923-29:1) kín ọ̀rọ̀ yìí lẹ́yìn nígbà tí ó wí pé, “the symbolic forms of a society constitute its culture…” Èyí tí ó túmọ̀ sí pé “àwọn ẹ̀yà àrokò àwùjọ wà nínú àṣà àwùjọ”. Gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú àsìá orílẹ̀-ede Nàìjíríà, àwọ̀ ewé tí ó wà ní apá ọ̀tún àti òsì dúró fún ilẹ̀ ọlọ́ràá Nàìjíríà àti iṣẹ́ àgbẹ̀, ọrọ̀ ńlá orílẹ̀-ede àti adùn rẹ̀ pẹ̀lú ilẹ̀ tí ó dára fún ohun ọ̀gbìn, nígbà tí àwọ̀ funfun tí ó wà ní ààrín dúró fún àlàáfià àti ìṣọ̀kan, (ìfọ̀kànbalẹ̀ tó péye). Torí náà a le sọ pé, ṣíṣe àmúlò àmì fún ìtọ́ka sí òye tàbí ohun kan nípa fífún un ní ìtumọ̀ tí ó yàtọ̀ sí ìtumọ̀ àdání tirẹ̀ ni à ń pè ní àrokò. Ó ń fún wa ní ìtumọ̀ tí ó jinlẹ̀, tí ó sì ṣe pàtàkì. Èyí ló mú kí Smith (1952:13) fi kún un pé:

> All things used as symbol must be something that is well known in literature and culture, when one understands the symbol being used, one connects its meaning to the story one is reading or films you are watching and understand the story in a deeper level.
> (Gbogbo àwọn ohun tí à ń lò gẹ́gẹ́ bí àrokò gbọ̀dọ̀ jẹ́ ohun tí a mọ̀ nínú lítíréṣọ̀ àti àṣà, nígbà tí ènìyàn bá ní òye àrokò tí a lò, ènìyaǹ yóò lọ́ ìtumọ̀ rẹ̀ mọ́ ìtàn tí ó ń kà, tàbí fíímù tí onítọ̀hun ń wò, ìtàn náà yóò sì yé e yéké-yéké.)

Àyọlò òkè yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé, ohun tí ènìyàn mọ̀ dájú dájú nínú lítíréṣọ̀ àti àṣà àwujọ ni wọn máa ń lò gẹ́gẹ́ bí àrokò.

## Àrokò Gẹ́gẹ́ bí Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Láàárín àwọn Babaláwo

Babaláwo ni àwòrò ifá tí ó jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá. Ẹ̀dá tí ifá yàn láti jẹ́ alárinnà láàrin ènìyàn àti Ọ̀rúnmìlà ni, ìdí nìyí tí àwọn ènìyàn àwùjọ fi máa ń lọ ṣe àyẹ̀wò lọ́dọ̀ babaláwo nígbà tí nǹkan bá rú wọn lójú nínú ìrìnàjò ayé wọn. Wọ́n máa ń fẹ́ ìtọ́nisọ́nà àti ìlanilóye lórí àwọn ohun tó rújú wọ̀nyí torí náà àwọn ènìyàn máa ń lọ sí ọ̀dọ̀ babaláwo nígbà gbogbo láti bèèrè ọgbọ́n àti ìlànà lórísìírísìí lọ́wọ́ Ifá. Ohun èlò tí àwọn babaláwo fi ń ṣe àyẹ̀wò ni ikin, ọ̀pẹ̀lẹ̀, ìrọ́kẹ́ òyèrosùn, bákan náà, wọ́n a sì máa ń ki ẹṣẹ ifá lákòókò àyẹ̀wò wọn. Èyí já sí pé ohun èlò ifá fún àyẹ̀wò le jẹ́ àrídìmú tàbí ohùn ẹnu.

Gẹ́gẹ́ bí a ti fi yé wa ṣaájú pé ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tó jinlẹ̀ ni àrokò jẹ́ láwùjọ Yorùbá, èyí ló jẹ́ kí àwọn babaláwo mú un lọ́-kùn-ún-kún-dùn láti le ní àṣírí láàárín ara wọn gẹ́gẹ́ bí awo. A ti ṣàlayé síwájú pé àrokò le jẹ́ ọ̀rọ̀ ẹnu, ó sì le jẹ́ ohun èlò àrídìmú, díẹ̀ lára àwọn ohun ìpàrokò àrídìmú àti àwọn ọ̀rọ̀ alárokò tí wọ́n máa ń lò fún ìbánisọ̀rọ̀ láàárín ara wọ́n ni ìwọ̀nyí:

## Àwọn Ohun Èlò Àrídìmú fún Ìpàrokò láàárín àwọn Babaláwo

**Ìrùkẹ̀rẹ̀:** Ìrù mààlúù ni wọ́n fi ń ṣe ìrùkẹ̀rẹ̀ ifá, ó le funfun, ó le jẹ́ pupa, ó sì le jẹ́ dudu, ohun èlò tó gbajú-gbajà ni ìrùkẹ̀rẹ̀ jẹ́ láwùjọ Yorùbá. Ìdí ni pé ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ohun ẹ̀ṣọ́ ọba, èyí tí wọ́n máa ń lò láti fi kí akẹgbẹ wọn, ìjòyè tàbí àwọn ara ìlú. Àmọ́ ṣá, kì í se kábíyèsí nìkan ni ó lẹ́tọ̀ọ́ sí lílo ìrùkẹ̀rẹ̀, àwọn babaláwo náà máa ń mú un lọ́wọ́ gẹ́gẹ́ bíi àrokò tí ń ṣàfihàn ipò wọn gẹ́gẹ́ bí i, alárinà láàrin Ọrúnmìlà àti ènìyàn láwùjọ. Wọ́n sì tún máa ń lò ìrùkẹ̀rẹ̀ yìí láti pàrokò kí awo ẹgbẹ́ wọn, pàápàá jù lọ nígbà tí wọn bá pàdé, ṣùgbọ́n tí kò sí àǹfààní láti bára wọn sọ̀rọ̀ nítorí ìdí kan tàbí òmíràn, ìrùkẹ̀rẹ̀ yìí ni wọn yóò mì sí ara wọn gẹ́gẹ́ bí ìkíni. Èjì Ogbè kín ìṣe yìí lẹ́yìn nígbà tí ó wí pé:

Gẹ̀gẹ́gẹ̀ ni wọn ń kan kósó
Gùdùgùdù, ni wọn ń lu àrán Òrìṣà
Bí babaláwo méjì bá ríra wọn
Wọn a máa ṣèrùkẹ̀rẹ̀ yẹtúrú yẹtúrú
A difá fún Orí
Nígbà tí ń tìsàlú Ọ̀run bọ̀ wálé ayé
Wọ́n ní ẹbọ ni kó se
Kó le ba à dẹni àpésì ló rúbọ sí
Ǹjẹ́ orí rere ni tìrẹ

Ìrere ò lórí àá gbẹ́rù lé
Orí rere ni tìrẹ.
Ṣounde (1965:17)

Ò hàn gbangba nínú ẹsẹ-ifá tí a kì sókè yìí wí pé àwọn babaláwo maá ń wá orísìírísìí ọ̀nà láti kí ara wọn lábẹ́ àkóso bó ti wù kó rí. Mími ìrùkẹ̀rẹ̀ sí ara wọn lákòókò tí wọn bá pàdé yìí dúró gẹ́gẹ́ bí àrokò ìkíni pé ṣàlàfíà ni, nígbà ti babaláwo kejì náà yóò sì mi ìrùkẹ̀rẹ̀ padà gẹ́gẹ́ bíi àrokò láti sọ pé dáadáa ni.

**Ọ̀pá Osù/ Osùn.** Èyí ni ọ̀pá irin gígùn tí àwọn babaláwo máa ń gbé lọ́wọ́. Ọ̀pá yìí ní wọ́n rọ ẹyẹ sí ní téńté orí rẹ̀. **Osù** ni wọ́n ń pè é ní agbègbè Rẹ́mọ àti Ìjẹ̀bú nígbà tí Ọ̀yọ́ àti agbègbè rẹ̀ yòókù sì ń pè é ní **Osùn**. Ọ̀ràn-an-yàn ni ọ̀pá yìí jẹ́ fún gbogbo babaláwo láti ní ní àrọ́wọ́tó. Ọ̀pá yìí tún dúró gẹ́gẹ́ bí Ọ̀rúnmìlà nínú ilé awo, ìpéjọpọ̀ tí a bá sì ti kófìrí ọ̀pá yìí ó dúró gẹ́gẹ́ bí àmì láti fi hàn pé àwọn babaláwo wà níbẹ̀. Adéoyè (1985) ṣàlàyé pé, ọ̀pá yìí ni àrokò pàtàkì tí ifá ní, igun ilé ni wọ́n máa ń fi ọ̀pá yìí sí ní ìgbàkígbà tí wọn kò bá mú un lọ́wọ́. Ó tún fi yé wa síwájú sí i pé, ní agbo ilé mìíràn, ìdí Ìjoríwo ni wọ́n ọ́n ṣe àyè sí fún ọ̀pá Osùn. Àkùkọ adìyẹ ni wọ́n máa ń lò lati fi bọ ọ́, ní èyí tí ẹnikẹ́ni kò sì gbọdọ̀ jẹ nínú rẹ̀. Ò̀òró gan-gan ni ọ̀pá Osù/ Osùn gbọdọ̀ wà ní ìyẹ̀wù awo. Láti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọ̀pá yìí kò gbọdọ̀ wà ní ìdùbúlẹ̀, Awo Fátósìn[1] tan ìmọ́lẹ̀ sí i láti inú Odù Ọ̀ṣẹ́-ìrẹtẹ̀ (Ọ̀ṣẹ́ lọ̀tún, Ìrẹtẹ̀ lósì):

A sẹ́bì sílẹ̀ ajà ń rojú
Àìsẹ́bì sílẹ̀ ajá ń rojú
Ìpọ̀nrí ajá setán wọn ò jobí rí
Ẹ̀kọ lajá ti ń jẹ dé láéláé
A díá fún kékéje tí ń báwọn gbóde ìrànjè
A díá f`ósù gàgàgà tí ń báwọn ìsẹ́rimọmogbe
Adíá fún Gbénró tí í se yèyé Osù
Ǹjẹ́ Osù gbóríró, kó o má dùbúlẹ̀
Ìdúró gan gan làá bósù awo.

Odù tí a kì sókè yìí túbọ̀ fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìdúró gangan losù awo máa ń wà ní gbogbo ìgbà. Ṣùgbọ́n ṣá o, ní ìgbà mìíràn, Osù le wà ní ìdùbúlẹ̀, èyí tí ó dúró gẹ́gẹ́ bí àrokò fún ìpapòdà awo. Bí babaláwo bá gbésẹ̀, wọn yóò dùbúlẹ̀ ọ̀pá Osù sí àbáwọlé rẹ̀, èyí sì dúró gẹ́gẹ́ bíi àrokò itúfọ̀ fún àwọn awo àti aládùúgbò awo tó gbésẹ̀, láti jẹ́ kí wọ́n mọ̀ pé babaláwo náà ti gòkè àjà. Lóòró gangan tósù gbọ́dọ̀ wà ló fa sábàbí orin tí àwọn babaláwo máa ń kọ pé:

---

1 Awo Fátósìn ni àarẹ asùnyẹ̀rẹ̀ fún ilú Ogoje. Ó ń gbé ní nọmba 7 Agbowó street, Ibadan. Ó sọ ìtumọ̀ osù fún wa, ó sì ki Odù ifá Ọ̀ṣẹ́ ìrẹtẹ̀ láti fi ìdí ọ̀rọ̀ rẹ̀ múlẹ̀ ni ilé iṣẹ̀ rẹ̀ ní ọjọ́ kẹfà, Osù kejì, ọ̀dún 2020.

Osù mórí ró
Kó o má dùbúlẹ̀
Lóòró gangan làá b`Osù
Osù mórí ró
Kó o má dùbúlẹ̀
Lóòró gangan làá b`Osù awo o.

Orin yìi ṣe ìtẹnumọ́ ipò tí osùn máa ń wà ni.

**Idè** jẹ́ ohun èlò ìdámọ̀ tàbi ọ̀kan lára àwọn ohun ọ̀ṣọ́ fún àwọn babaláwo. Ìlẹ̀kẹ̀ ni ìdè yìí, èyí tí ó sì jẹ́ pé àwọn babaláwo ni ó ń lò ó. Ìlẹ̀kẹ̀ yìí kì í ṣe fún gbogboògbo, ẹlẹ́sìn kọ̀ọ̀kan ló ni tirẹ̀. Ìdè yìí ní àwọ̀ méjì. Èyí tí ó jẹ́ àwọ̀ ewé ni wọ́n ń pè ní 'Otútù' nígbà tí wọ́n ń pe èyí tí ó jẹ́ aláwọ̀ omi wúrà ní 'Ọpọ̀n'. Àwọn ìdè méjèèjì yìí ni wọ́n papọ̀ tí wọ́n fi ṣẹ̀dá ìdè tí àwọn babaláwo ń lò fún ọ̀ṣọ́-ọrùn tàbí tọwọ́. Yàtọ̀ sí lílò fún ẹ̀ṣọ́ ara, àrokò àmì ìdáààbò bò ni ó jẹ́ fún babaláwo àti àwọn ọmọ awo. Ó jẹ́ àrokò "má fọwọ́ kàn án" fún àwọn ẹ̀mí àìrí àti ikú. Nígbàkúùgbà tí àwọn ẹ̀mí àìrí bá fojú kan ìdè yìí ní ara ẹníkan, kíá ni wọ́n yóó so ewé agbéjẹ́ mọ́wọ́, torí pé àrokò yìí yóò ti pe àkíyèsí wọn sí i pé ẹni náà kì í se ènìyàn lásán. Odù Ọ̀kàràn sodè, (Ọ̀kàràn lọ́tun Ogbè lósì) fi idí ọ̀rọ̀ yí múlẹ̀, ifá ní;

Ọ̀kànràn sodè so gbàlàjà
A dífá fún Sófúnmiláyọ̀ tí í sobìnrin Àgbọmìrègún
Níjọ́ to lọ bú ìyá ikú lọ́jà Ejìgbò mẹkùn
Ẹbọ lawo ní ó ṣe.

Obìnrin Àgbọmìrègún ni Ṣófúnmiláyọ̀, òun ni ó lọ nájà ni ọjà Ejìgbò mẹkùn tó bú ìyá ikú. Nígbà tí ìyá ikú délé, ó sọ fún ọmọ rẹ̀ pé ìyàwó Ọ̀rúnmìlà bú òun lọ́jà. Nígbà tí Ṣófúnmiláyọ̀ délé òun náà sọ fún Ọ̀rúnmìlà, ó wí pé òun ti mọ̀ pé bí ìyá ikú bá délé yóó sọ fún ọmọ rẹ̀, ìdí nìyí tó fi tètè fi tó Ọ̀rúnmìlà létí ki àwọn le ba à mọ ohun tó kàn ní ṣíṣe. Ọ̀rúnmìlà dífá, Odù Ọ̀kàràn sodè ló jáde, àwọn aláwo Ọ̀rúnmìlà ki ifá náà, wọ́n sì sọ fún un kí ó so idè mọ́ ọrùn ọwọ́ ìyàwó rẹ̀, ó sì rúbọ, ó ṣètùtù, wọ́n ní kí ó gbé ẹbọ náà ka iwájú ilé. Nígbà tí ikú ń bọ̀ pẹ̀lú ìbínú rẹ̀, ó bá ẹbọ ní ìdì Èsù, Èṣù bèèrè lọ́wọ́ rẹ̀ pé ibo ni ó ń lọ, Èṣù dáhùn pé òun fẹ́ lọ pa ìyàwó Ọ̀rúnmìlà tó bú ìyá òun lọ́jà Ejìgbò mẹkùn. Èṣù wá gba ikú níyànjú pé kí ó jẹun kó tó lọ kojú Ọ̀rúnmìlà torí pé ẹ̀dá alágbára ni. Ikú jẹun tán, ó fẹ́ máa lọ, Èṣù wá sọ fún ikú pé Ọ̀rúnmìlà ló wá oúnjẹ tí ó jẹ, kílódé tí ó sì tún pinnu láti pa ìyàwó rẹ̀, nígbà tí ikú dé ọ̀dọ̀ Ọ̀rúnmìlà, ó rí i pé Ọ̀rúnmìlà ti fi ìdè de ìyàwo rẹ̀ mọ́lẹ̀, Èṣù bèèrè pé kí ló dé tí ó fi ìdè so ìyàwò rẹ̀, Ọ̀rúnmìlà sì dáhùn pé, nítorí pé ó bú ìyá ìwọ ikú ni òun ṣe dẹ̀ ẹ́, kí òun le fi ìyà jẹ̀ ẹ́, ikú sì dáhùn wí pé orí yọ Ṣófúnmiláyọ̀ pé òun fẹ̀ pa á ni tẹ́lẹ̀,

láti ìgbà yìí ni Ọ̀rúnmìlà àti ikú ti mulẹ̀ pé gbogbo ẹni tí ikú bá ti rí ìdè lọ́wọ́ rẹ̀, kí ó fi ọ̀wọ̀ òun Ọ̀rúnmìlà wọ̀ olúwa rẹ̀, kó má ṣì ṣe wọ́n níbi. Láti ìgbà náà ni àwọn babaláwo àti ọmọ awo ti ń lo idè gẹ́gẹ́ bí i àrokò àábò. Odù ifá yìí fi ìdí ìtàn tí ó rò mọ́ bí idè se di nǹkan ìpàrokò àábò láàrin àwọn babaláwo múlẹ̀.

**Ìrọ̀kẹ́** jẹ́ ohun èlò tí àwọn babaláwo máa ń mú lọ́wọ́. Ó ní ihò kan ní ìdí, inú ihò yìí ni irin kékeré kan wà, èyí sì máa ń dún bíi aago nígbà tí wọ́n bá ń mì-ín. Yàtọ̀ sí pé wọ́n ń lò ó láti pàrokò, àrokò ni ohun fúnra rẹ̀. Nígbà tí a bá rí ìrọ̀kẹ́ lọ́wọ́ ẹnìkan, láìsí àní-àní, a óò ní òye pé babaláwo ni ẹni tí ó mú un lọ́wọ́, èyí ni pé ìrọ̀kẹ́ jẹ́ àrokò/àmì tí ń ṣàfihàn babaláwo láwùjọ Yorùbá. Àwọn babaláwo tún máa ń lò ìrọ̀kẹ́ fún ìkíni àti fún ìjẹ́rì sí ohun kan. Àwọn babaláwo a máa lo ìrọ̀kẹ́ gẹ́gẹ́ bí àrokò láti fi ẹ̀rí tó dájú múlẹ̀ pé òdodo ni ifá tí ọmọ awo ń kì. Nígbà tí ọmọ awo bá ń ki ifá tí ó tọ̀nà fún ẹni tí ó wá fún àyẹ̀wò, babaláwo mìíràn tí ó wà ní ìjókòó yóò fi ìrọ̀kẹ́ lu etí ọpọ́n ifá lẹ́ẹ̀mẹta, lílù etí ọpọ́n ifá yìí dúrò gẹ́gẹ́ bí àrokò láti jẹ́rìí pé ifá tí ọmọ awo ń kì jánà. Odù Ogbè Ògúndá fi ìdí èyí múlẹ̀ nígbà tí wí pé:

Òtítọ̀ wọ́n kò sí láyé mọ́
Orúkọ tí à á pe ìrọ̀kẹ́
Ifá ní eléyìun kò gbọdọ̀ dá sí ọ̀rọ̀ tòun mọ́ láé láé
Bí wọ́n bá ń dá'fá
Kí wọn kó má a fẹnu rẹ̀ ṣẹpọ́n ko ko ko...[2]

Ifá tí a kì sókè yìí fi kókó ọ̀rọ̀ múlẹ̀ pé, fífi ìrọ̀ké lu etí ọpọ́n ifá jẹ́ àrokò láti fi òdodo ifá tí awo ń kì múlẹ̀. Àrokò yìí sì má a ń mú ìwúrí wá fún ọmọ awo láti túbọ̀ ní ìgboyà sí i nínú iṣẹ́ awo.

**Ewé Akòko**. Láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, ìran Yorùbá kò kóyán ewé àti egbò kéré rárá nínú àṣà àti ìṣe wọn, torí pé wọ́n mọ iṣẹ́ àti ìwúlò rẹ̀ dójú àmì débii pé wọ́n tún máa ń ṣámúlò rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àrokò fún ìbánisọ̀rọ̀ awo. Ó ṣeé ṣe kí a rí àmúlò àwọn ewé tàbí àrokò oyè mìíràn ní àgbègbè mìíràn. Èyí ló jẹ́ kí Ògúndèjì (1997:151) ṣàlàyé pé *the symbolic-object or its content may however vary from one geographical context to another,* "ohun èlò ìparokò tàbí àkóónú rẹ̀ le yàtọ̀ sí ara wọn láti agbègbè dé agbègbè". Àwọn babaláwo a máa lo ewé akòko fún àrokò, ìtumọ̀ tó yàtọ̀ ní ewè akòko ní láàárín àwọn awo, fí fi ewé yìí ránṣẹ́ sí ara wọn jẹ́ arokò fún ìpeni síbi ayẹyẹ ìwúyè. Nìgbá tí awo kan bá fi ewé yìí ranṣẹ́ si awo mìíràn, ó túmọ̀ sí pé, àwọn ọmọ ẹgbẹ́ awo ti yan ẹni tí ó fi ewé yìí pàrokò ránṣẹ láti jẹ oyè kan nínú ẹgbẹ́ awo, ó sì ń fi àkókò yìí pe ẹni tí ó fi ewé náà ránṣẹ́ sí láti wáá yẹ́ òun sí lọ́jọ́ ayẹyẹ ìwúyè náà.

**Ewé Òrúwọ**. Ọ̀kan lára àwọn ewé tí àwọn babaláwo ń lò fún àrokò ní Òrúwọ. Àwùjọ Yorùbá pàápàá rí Òrúwọ gẹ́gẹ́ bi ewé tí ó dára fún ìgbógunti

2 Awo Fatosin ni ó ki odù-ifá yìí fún mi

àrùn ibà àti àwọn àìsàn pẹ́pẹ̀pẹ́ mìíràn. Àwọn babaláwo máa ń lò ó láti pàrokò àìsàn òjijì tó le la ẹ̀mí lọ. Nígbà tí babaláwo bá ń tọ́jú aláìsàn kan, tí ó sì nílò ìrànlọ́wọ́ kíákíá láti ọ̀dọ̀ akẹgbẹ́ rẹ̀ fún ìtọ́jú aláìsàn náà, babaláwo yóò pọ́n ewé Òrúwọ légbìnrìn ránṣẹ́ sí akẹgbẹ́ rẹ náà. Bí ẹni náà bá sì ti rí àrokò yìí, yóò ti mọ̀ pé ẹnìkan ní sàkání awo tó fi àrokò yìí ránṣẹ́ ń ṣàárẹ̀ gan-an, wọ́n sì nílò ìrànwọ́ àwọn awo yóòkù ní kíákíá. Fún ìdí èyí, lọ́gán ni awo yóò díde láti lọ ṣèrànwọ́ fún ẹni tó pàrokò naà. Irú ìrànwọ́ ṣíṣe fún ẹni yìí ni ó hàn nínú òwe Yorùbá pé “awo ní gbáwo nígùnwọ́, báwo ò bá gbáwo nígùnwọ́, awo a fọ́, awo a ya, awo a fàtẹ tẹ́dìí”.

**Ìbò ajé**: ìbò ajé jẹ́ ohun èlò ìpàrokò fún ìbánisọ̀rọ̀ lákàtà àwọn babaláwo ní àwùjọ Yorùbá. Babaláwo máa ń lò ó láti fi jíṣẹ́ fún ẹni tó wá dífá. Láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni Ifá fúnra rẹ̀ ti yan ìbò gẹ́gẹ́ bí aṣojú rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú Ogbègúndá. Ìtàn fi yé wa pé ọmọ ìkọ́fá ni ìrókọ̀, ìrùkẹ̀rẹ̀, ọpọ́n àti ìbó jẹ́ ní ilé Àgbọnnìrègún. Lẹ́yìn ìgbà tí baba ti kọ́ wọn ní ifá dunjúdunjú. O pinnu láti lọ ìrìnàjò, baba fun ìrókọ̀ ní ewúrẹ́ láti tọ́jú rẹ̀ de òun, o fún ìrùkẹ̀rẹ̀ ní àgùntàn, o fún ọpọ́n ní adìyẹ, nígbà tí ó sì fún ìbò tí í ṣe ẹni ìkẹyìn ní ẹyẹlé. Irọ́kọ̀, ìrùkẹ̀rẹ̀ àti ọpọ́n kò tọ́jú àwọn ohun ọ̀sìn yìí bó ṣe yẹ, ṣùgbọ́n ìbò mójú tó tirẹ̀ dáadáa. Nígbà tí baba ti àjò dé, inú rẹ̀ bàjẹ́, o sì wí fún àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí kó se dáadáa pé kí wọ́n má ṣe dá sí ọ̀rọ̀ òun mọ́ àfi ìbò níkan tí í ṣe ọmọ ọ̀dọ̀ rere. Ifá ní:

...orúkọ tí à á pe ìránṣẹ́ (ìbò)  
Ifá ní ìbò nìkan ni kí ó má a dá sí  
Ọ̀rọ̀ tòun ní gbogbo ìgbà  
Ǹjẹ́ kí ní ń bẹ lẹ́yìn tí ń tubọ?  
Ìrànràn  
Ìránṣẹ́ níkan ní ń bẹ lẹ́yìn tí ń tubọ  
Ìrànràn  
Ǹjẹ́ kí ni yóò má à rànwá ṣe?  
Ìrànràn  
Ifá yóò má a rànwá ṣe  
Ìrànràn[3].

Ifá tí a kì yìí fi pàtàkì ìbò múlẹ̀. Ìbò yìí lè jẹ́ owó ẹyọ, egungun, kóró àgbálùmọ̀ tàbí ohun mìíràn tí ó bá àṣa àti ìgbàgbọ́ agbègbè kọ̀ọ̀kan mu. Bí àpẹẹrẹ owó-ẹyọ ń pàrokò ‘ire’, nígbà tí egungun sì ń pàrokò ‘ibi’ tàbí ‘ohun líle’. Yàtọ̀ sí èyí, bí babaláwo kan bá fi Ìbò ajé ránṣẹ́ sí babaláwo mìíràn, èyi túmọ̀ sí pé, wọ́n ń pè é sí ohun kan tó ní í sẹ pẹ̀lú Ifá, yálà láti wá dífá fún ẹnìkan tó ń kojú ìṣòro, ẹnìkan tó ń ṣàìsàn níbìkan tàbí kí ó jẹ́ ìpè fún ìpàdé tó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ Ifá.

3 Ẹnu Awo Fatosin ni a ti gba èyí

**Èédú áti Òkuta:** èyí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ohun èlò ìparokò fún ìbánisọ̀rọ̀ awo. Èédú ń pàrokò sísun, nígbà ti òkuta sì ń pàrokò gígún. Ọ̀nà àṣírí láti bèèrè ìbéèrè awo ni àrokò yìí, ó sì máa ń wáyé nígbà ti babaláwo ba nílò ìtọ́ni làti ọ̀dọ̀ àwọn akẹgbẹ́ rẹ̀ tàbí àwọn tó lóye àti ìrírí jù ú lọ lórí òògùn tí ó ń ṣe. Bí babaláwo kan bá fi èédú àti òkuta ránṣẹ́ sí babaláwo mìíràn, ohun tí ó ń bèèrè ni pé, ṣé òun yóò gún un ni, àbí òun yóò sun ún níná. Bí wọ́n bá dá òkúta padè, ó túmọ̀ sí pé yóò gún un ni ṣùgbọ́n bí wọ́n bá dá èédú padè , èyí ni pé sísun ni nǹkan náà. Ìgbà mìíràn wọ́n sì le dá méjéèjì padà ní èyí tí ó túmọ̀ sí pé, wọn yóò sun ún, wọn yóò sì tún gún un.

**Igbá tàbí Ìkòkò amọ̀**, Bí a ti ṣe mọ̀ pé ìrísí àrokò le má ní ìjọra pẹ̀lú ohun tí a fi wé, ṣùgbọ́n ìtumọ̀ tí a fi fún un jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà láwùjọ. Kẹ́hìndé (2016:23) ṣàmúlò ọ̀rọ̀ Ògúndèjì (1997) tí ó wí pé, onírúurú ìtumọ̀ ni a le fún àrokò, ìtumọ̀ náà sì ní í ṣe pẹ̀lú àṣà, ìgbàgbọ́, àti ìwòye ẹnikọ̀ọ̀kan. Igbá tàbí ìkòkò amọ̀ ní àrokò tí àwọn awo máa ń lò láti fi ara wọn hàn fún akẹgbẹ́ wọn. Èyí máa ń wáyé pàápàá jù lọ nígbà tí awo kan bá wà ní ọ̀nà-àjò, tí ilẹ̀ sì ṣú, tí kò sì rí ibi tí yóò sùn di ọjọ́ keji. Bí babaláwo náà bá lọ sí ilé aláwo tí ó wà ní agbègbè ibẹ̀, tí ó fún babaláwo náà ní igbá tàbí ìkòkò amọ̀, babaláwo náà yóò gbà á lálejò tọwọ́-tẹsẹ̀ bẹ́ẹ̀ sì ni yóò tọ́jú rẹ̀ dáadáa. Èyí ṣe àfihàn àwọn àrokò kan tó sẹ́yọ nínú òwe Yorùbá tí ó wí pé, “igbá ilé tilé ní í ṣe, àwo ilé tilé ní í ṣe.” Tí ó tumọ̀ sí pé ẹni tó dé yìí, ọmọ ìyá àwọn ní í ṣe.

## Àwọn Ìpèdè Alàrokò láàárín àwọn Babaláwo

**Àbọ̣rúbọ̣yè**. Èyí ni ìpèdè alárokò tí ó máa ń jáde látẹnu àwọn babaláwo tàbí láàárin babaláwo áti èni tí ó wá sí ọ̀dọ̀ rẹ̀ fun àyẹ̀wò nígbà tí wọ́n bá ń kíra wọn. Dípo lílo ìkíni gbogboògbò bíi ‘ẹ káàárọ̀/káàsán/káalẹ́’, àbọrúbọyè yìí ni wọ́n máa ń ṣàmúlò nígbà yòówù tí wọ́n  bá fẹ́ kí ara wọn. Èyí jẹ́ àrokò pé ẹni tí ó kíni pẹ̀lú ìpèdè yìí jẹ́ awo, oníbàárà tàbí ẹni tí ó tún mọ irúfẹ́ babaláwó tí ó sì mọ̀ nípa ìkíni Yorùbá ajẹmẹ́sìn. Yàtọ̀ sí pé a fi ń ṣe àrokò ìkíni, ó tún máa ń dúró gẹ́gẹ́ bí ìwúre nínú ẹgbẹ́ awo, èyí tí ‘Àbọrú’ túmọ̀ sí pé “ohun tí à ń bọ yóò rú”, “rú” nínú ìpèdè yìí túmọ̀ si pé “ohun tí à ń bẹbẹ̀ fún yóò di mímúṣẹ. Nígbà tí ‘bọyè’ sì túmọ̀ sí, ‘a ó ṣoríire níbẹ̀ o.’ A ó rí i pé yàtọ̀ sí pé ó jẹ́ ìkíni ajemẹ́sìn, ó tún ṣe atọ́nà fún iṣẹ́-awo tí ẹni náà ń ṣe.

**Eríwoyà**, èyí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ìpèdè alárokò tí àwọn babaláwo máa ń lò lákòókò tí wọ́n bá fẹ́ ìdákẹ́ rọ́rọ́ nínú agbo wọn. Eríwoyàn túmọ̀ sí pé “kí kẹ́kẹ́ ó pa rére” èyí ni pé, kí wọ́n sinmi ariwo. Nígbà tí àwọn babaláwo bá wà ní ìpéjọpọ̀ kan, tí àríyànjuyàn tàbí ohun kan fa ariwo láàárín ara wọn, tàbí tí ọ̀kan lára àwọn ọmọ ẹgbẹ́ bá fẹ́ sọ̀rọ̀, bí ó bá ti pèdè alárokò yìí lẹ́ẹ̀mẹta léra léra, “Eríwoyàn Eríwoyàn Eríwoyàn” gbogbo àwọn ọmọ ẹgbẹ́ yóò sì dáhùn wí pé, “àyàgbó, àyàtọ̀, àyà ọmọ eríwo ọ̀ṣìn pé”. Lẹ́yìn ìpèdè yìí gbogbo wọn yóò

ìdákẹ́ rọ́rọ́. A le sọ pé ìpèdè àrokò yìí ń ṣiṣẹ́ ìkóni-níjanu fún àwọn babaláwo àti ọmọ awo.

**Eépà ifá àti Gbéere**, ìpèdè alárokò yìí máa ǹ jẹyọ nígbà tí babaláwo tàbí ẹnìkan bá ń kifá tàbí sùnyẹ̀rẹ̀, tí ẹ̀gùn ìyẹ̀rẹ̀ sí gùn irú ẹni bẹ́ ẹ̀, àwọn tó wà pẹ̀lú rẹ̀ yóò fọhùn wí pẹ́, "eépà ifá" tí ó túmọ̀ sí pé "a gbóríyìn fún ifá". Bí wọ́n ba sì tún sọ pé "gbéere" (gbé e re, tàbí kàre) èyí túmọ̀ sí ìgbóríyìn fún ẹni tí ń sùnyẹ̀rẹ̀ náà, ó sì dúró gẹ́gẹ́ bí àrokò láti jẹ́ kí ẹni náà mọ̀ pé ó ń ṣe é ní bí ó tí tọ́ àti bí ó ti yẹ. Iṣẹ́ ìgbóríyìn fún ifá àti ẹni tí ń sùn ìyẹ̀rẹ̀ ni ìpèdè alárokò méjéèjì yìí ń ṣe.

**Eépà odù àti Á gbà á tè tè tè**, wọ́n máa ń pèdè alàrokò wọ̀nyí nigbà tí àwọn babaláwo bá dárúkọ àwọn odù kan, tí ó jẹ́ odù tó lágbára, tí ó sì fìdí múlẹ̀ gan an torí náà, wọ́n ń lo àrokò yìí láti gbóríyìn fún àwọn odu ná àn. Fún àpẹẹrẹ, nígbàkúùgbà tí wọ́n bá dárúkọ Odù Òfún Méjì, tàbí Ọ̀rọ̀gún Méjì ní ibikíbi, gbogbo àwọn Awo tí ó bá wà ní àyíká ibẹ̀ gbọ́dọ̀ dáhùn pé "eépà odù" ní èyí tí ó túmọ̀ sí pé "a kan sáárá sí ọ o", wọ́n ń fi àrokò yí kan sáárá sí Odu tí wọ́n dárúkọ ní àkókò náà. Òmíràn tí ó tún fara pẹ́ irú odù yìí ni Odù Ọ̀ṣẹ̀ Turá, odù yí ni ìwádìí fi yé wa pe òhun ni odù tó máa ń gba ẹbọ, torí náà kò sí bí a ṣe le rúbọ tí a kò ní pe odu Ọ̀ṣẹ́ Tura sí i. Bí wọ́n bá pe odù Ọ̀ṣẹ̀ Turá níbikíbi, pàápàá jùlọ ní ojúbọ, àwọn babaláwo tó wà níbẹ̀ gbọ́dọ̀ sọ pé, "á gbà á tè tè tè" èyí ni pé, ẹbọ wọn yóó gba ní kíákíá. Ìwúre kí ẹbọ wọ́n tẹ̀tẹ̀ fín ni ìpèdè alárokò yí jẹ́.

**Ìsokò àti igba**, àrokò yìí wọ́pọ̀ ní agbègbè Ìjẹ̀bú àti ẹ̀gbá, nígbà tí babaláwo kan bá ń ki ifá, tí ó sì dé ìkóríta láti dárin sí odù ifá tí ń kí ni yóò sàmúlò ìpèdè alárokò yìí láti sín àwọn babaláwo tó wà níbẹ̀ ni gbẹ́rẹ́ ìpàkọ́ pé òun fẹ́ kọrin. Èyí dàbí irú ìpèdè tí àwọn ọdẹ máa ń lò nígbà tí wọ́n bá fẹ́ dárin, tí wọn yóò wí pé, "ẹ́ ẹ́ gberin ọdẹ àbí ẹ ẹ̀ gberin". Ìsokò túmọ̀ si "mo fẹ́ dárin" nígbà tí "Igba" túmọ̀ sí "dárin náà ká gbọ́". Fún àpẹẹrẹ, nígba tí babaláwo bá ń ki ifá wí pé;

Ìtarúkú ní í ṣawo ìtarúkú
Ìtarùkù ní í ṣawo ìtarùkù
Ìtarùkù ta ta ta
A dífá fún ìgbà tí ń ṣawo ròde Ọ̀yọ̀
Ẹbọ lawó ní ó ṣe
Ó lanu kótó orin awo kó sí i lẹ́nu

Ní ìkórita yìí Babaláwo yóó wí pe, "Ìsokò" tí ó túmọ̀ sí pé "mo fẹ́ kọrin". Èyí ni àrokò fún ìtani lólobó pé níbi tí òun dé yí o, òun fẹ́ dárin. "Igba" túmọ̀ sí dárin náà ká gbọ́. Yóó sì kọrin wí pé;

Igba irúlá o

Igba irúkàn o
Báwá yẹ̀ ṣe lanígba
Igba irúlá
Igba irúkàn
Báwá yẹ̀ ṣe lanígba

Àrokò pàtàkì ni ìpèdè yìí láti jẹ́ kí àwọn awo yòókò mọ̀ pé òun fẹ́ kọrin.

---

Awo Fatosin ni ó ki odù-ifá yìí fún mi

## Ìkádìí

Iṣẹ́ yìí fi pàtàkì àrokò hàn nílẹ̀ Yorùbá, pàápàá láàárín àwọn babaláwo. Ó sì jẹ́ ká mọ̀ pé gbogbo iṣẹ́, òwò, ẹ̀sìn tàbí ẹgbẹ́ ni ó ní àrokò tirẹ̀ tí wọ́n ń lò fún ìbánisọ̀rọ̀ nínú ẹgbẹ́ kóówá wọn, ní èyí tí ẹni tó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ yóò lè mọ ìtúmọ̀ àròko náà ní kíkún. Àwọn babaláwo ni ìpèdè tí wọ́n fi lè ba ara wọn tàbí òrìṣà wọn sọ̀rọ̀ tí ìtumọ̀ rẹ̀ kò sí ní yé ògbẹ̀rì. Àrokò yìí, gẹ́gẹ́ bí a ti rí wọn nínú àpẹẹrẹ, lè jẹ́ ìpèdè, tàbí ohun èlò, tí wọ́n sì ní ìtumọ̀ ìjìnẹ̀ tiwọn. Iṣẹ́ yìí fìdí ẹ múlẹ̀ bákan náà pé àrokò máa ń fún babaláwo ní àǹfààní láti jẹ́ kí wọ́n ní àṣírí láàárín ara wọn. Nìtorí náà olúkúlùkù ọmọ Yorùbá gbọ́dọ̀ jí gìrì sí ṣíṣàmúlò àrokò gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ kí wọ́n sì fi kọ́ àwọn ọmọ wọn ní èyí tí yóò ṣe ìrànwọ́ fún ìdàgbàsókè àṣà àti èdè ní àwùjọ Yorùbá.

## Àwọn ìwé ìtọ́kasí

Abimbola, A. 1975. *Yorùbá Oral Tradition*. Selections from the papers presented at the seminar on Yorùbá oral tradition: poetry in music, dance and drama. Department African Languages and Literatures Literatures University of Ife, Ile- ifẹ̀ Nigeria

Adéoyè, C .L. 1985. *Ìgbàgbọ́ àti Ẹ̀sìn Yorùbá*. Evans Brothers (Nigeria Publisher) Limited Jericho Road, Ibadan.

Adéoyè, C .L. 2005. *Àsa àti Ìṣe Yorùbá*. University Press limited, Ibadan.

Adesanya, A.O. 2014. Objectific Codes in Nonverbal Communication in Yorùbá novels: Journal of Yorùbá studies Association of Nigeria. Vol. 7. No 3. 2014. Pg 261

Alamu, O.O. 2010. *Aesthetics of Yoruba film*. The research institute for the world
*Association*.

Backony, 1974. Non-verbal symbolism in feature film. *Journal of University film*


Cassirer, B. 1923. *Philosophie der symbolschen Formen*. Zweiter Teil: Das mythische Denken. Berlin: Bruno Cassirer. Translated as The

Philosophy of symbolic forms: Vol. 2: Mythical Thought. New Haven: Yale University Press, 1955.

Cobley, P. 2001. *Semiotice and linguistics*. Routledge, USA and Canada.
Eco U, 1976. *The theory of semiotics*. London, Indiana University Press.
Elliot G. 2010. *Media literacy and semiotics.* USA: Palgrave Macmillan.
Kẹ́hìndé A.O. 2016. Signs and Singifiactions in Saworoidẹ and Agogo Èèwọ̀. An M.A Project, Submited to Department of Linguistics and African Language, Faculty of Arts, University of Ibadan.
Marcel, D. 2004. *Message sign and meanings: A basic textbook in semiotics and communication thoery.* Canadian Scholars' Press Inc.
Ogúndèjì P A. 1988. A semiotics study of Dúró Ládipọ̀`s mythico-historical plays. A Ph.D Thesis, Department of Linguistics and African Language, Faculty of Arts, University of Ibadan.
Ògúndèjì, P.A. 1997. Oyin Adejọbi as a Dramatist: His life History, Influences and Sources. Ọmọ Alárẹ̀: Academic Journal of the Department of Nigerian Language and Literatures, Tai Solarin College of Education, Ìjẹ̀bú Ode, Vol. 1, No.1, pg 51-60
Ricardo and Joao, 2007. *Semiotics and intelligent system development*, the United State of America by idea group Publishing.
Shaleph, O. 2008. *Interactive media the semiotics of embodied interaction*. British: Library Cataloguing in Publication Data.
Ṣounde, F. 1965. Àkójọ Odù Ifá láti Inu Àwon Èjì Ogbè, Ọ̀yẹ̀kú Méjì, Ìwòrì Méjì àti Òdí Méjì. An M.A Project, Submited to The Institute of African Studies, University of Ibadan.

# Asomọ́
# Àwọn Àwòrán Ohun Èlò Ìpàrokò Àrídìmú tí a Ṣàlàyé Nínú Pépà Yìí







**Ire** ***Ọ̀rọ̀ kù sẹ́yìn*** **Ìkòkò**

Ìbò ajé







Osù/ Osùn Ìrọkẹ́ Idè









Akòko Òrúwọ Òkuta Èédú Ìrùkẹ̀rẹ̀